# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 917 LAGOS SATURDAY APRIL 25 – MAY 1 1964 KOBO MEJI (2D)


ALALA DE!

# Alhaji Kan Ni On Ri Anabi Nilu Medina

**MẸKA** — ọdun ni arinrin to b gẹ ti ẹnikan nja- awọn Alhaji ti o lọ lati ilu Ajaṣẹ (Potonovo) sa idun giri wipe on ls|a on ri Anọbi Muhamed ni oju orun ni ilu Mẹdina. Ilu Mẹdina ni ilu ti a bi Iya Oj ṣonla "Anọbi Muhamed. Pupọ ninu awọn Alhaji ni ko gba irohinyi gbọ, wọn sọ wipe Igbona ni o mba Alhaji na awọn miran ẹwẹ si sọ wipe, ẹni mimọ ni Alhaji ti o ri ojiṣẹ nla yi ni lati jẹ.

Irin ajo Mẹka ọdun ni ka mama fun awọn ara Nigeria. O to edẹgbarun (9,000) enia lọkunrin ati lobinrin ti nwọn wa si Mẹka na lati ilẹ Nigeria ni ọdun yi

Onirohin wa ni ni ijẹta ni nwọn gun Oke Arafat ti nwọn si pa ogunlọgọ ẹran, Ko sibi ti ri ni inu- ajo Mẹka na, gbogbo awọn enia wa ni nwọn wa ni alafia a fi awọn bi ẹgbẹrun ti nwọn nwukọ pẹlu awọn ti iba mu.

Dokita Anjorin Animashaun ti I ọb ran wa Mẹka lati ma tọju awọn enia wa ṣe gudugudu meje pelu awọn oluranlọwọ rẹ. Gbogbo awọn ti nwọn nṣe igbona fẹrẹ ni nwọn tọju patapata, a ko si ti gbọ wipe ẹnikan jala si ninu awọn eniọ wa na.

AKIYESI:
Irufẹ ala bawọnyi ti wa ti pẹ, ni asiko kan ni ilu Eko awọn Ẹgbẹ Serafu papa sọ wipe awọn ri Angẹli

—OLOTU

# Aboyun Kan Jomo Gbe Ni Ijebu

IJẸBU ODE— Adajọ Eharles O Madarik n sọ aboyun kan ti o ji ọmọ ọlọmọ gbe si ẹwọn ọdun mẹta ni kotu nla ni ijarun, Falilatu Kadiri ni orukọ obinrin aboyun na njẹ

Gẹgẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi obinrin na sun nwọn ni awọn ob ọmọ na ti nwọn sọ ni Adesuyi Olusẹsan fi ọmọ ... ni Imupa nwọn ko si ile ki obinrin yi to ji gbe.

Obinrin na ... nwọn pa mọ on on ko ji ọmọ ọlọmọ gbe rara, obinrin kan ti nwọn pe ni A h bi Osen ... o ni ki on ba on tọju ọmọ na, ... Ashao ... on ni on bi i.

Adajọ ... ni ọmọ- bi ... na npa on ko le dajin ... rara.

# Obinrin Kan Fi Owo Tanran Banbotu

LONDON—Adajọ Oyinbo kan ni ki obinrin ọlọla kan ti orukọ rẹ njẹ Lady Newtorongh fi adọta ponun tan ran fun ile rẹ ti awọn kan nlo fun ise agbere ni Davies Street, Mayfarr, London.

Awọn ọlọpa ni nigba kan ninu oṣu yi ọlọla obinrin yi gba owun ponun lọwọ obinrin kan ti o wa haya ilo lọwọ rẹ, iṣẹ bambotu ni obinrin na nṣe.

Awọn ọlọpa si ti nsọ ọ titi ki nwọn to wa mu iya onile yi. Loya rẹ sọro titi sugbon adajọ ni ki o fi adaọta ponun tanran ki o si ponun mẹdọgbon miran fun wahala awọn ọlọpa.

# Omoge Kan Fe Se Iyawo Elewon

LIVERPOOL — Ọmọge Oyinbo kan, Gillian Pierderg si eni ogun ọdun lọ si ọgba ẹwọn ni Liverpool lana, o lọ bẹ ọga awọn ẹlẹwọn wipe ki o jọwọ ki o gba on laye lati ṣe iyawo ọkunrin kan James Hussey ti nwọn tẹṣẹ ju sẹwọn ọgbọn ọdun ni ijẹjọ fun ole ti nwọn ja ninu reluwe.

A gbọ wipe o lọ wakati meji ti ọmọge na se ninu ọgba ẹwọn to mbẹ awọn ọga ẹwọn wi nwọn jọwọ jẹki James gbe on iyawo kakia A tun gbọ wipe ẹlẹwọn na tẹ pẹlọ ko tẹ on lọruu si k tu nisisiyi.

**AKIYESI: Wo oju ewe keta iwe yi ka bi Ogbon ati Lakaye ti yato.**

# Oloye Akintola Di Baba "Isale"

### Ola Ngori Ola

EKITI – Kosi bi oti ri ni ti ayoye oye ti Oloye Akintola je ni Erio ni ilu Ekiti ni ojo Satide ti o lo yi Oye tuntun ti a fun Olola S.L. Akintola ni "Baba Isale" Erio Ekiti Baba Isale Erio ni ilu Ekiti.



Oloye S. L. Akintola

Gbogbo awon Oba ati Ijoye ti o wa ni ilu na ni o fi owo si wipe Olola Oloye Akintola ni oye na osi ohun rebiribi ti o ti se si ile Yoruba

# Agbepo Laja Ko Jale

Lati Owo Wahabi Adesina

Awon okunrin meji kan bere si ba ara won jiyan lori oro kan wipe "Agbepo loja ko jale bi eniti o gba epo sile lowo re" Oro na di akitiyan de ipo ti awon mejeji ko ara won de iwaju oba ati agbalagba, oba si bere pe bawo ni ejo na tiri ?

Enik ni so wipe ko si eniti o kan eniti o gba epo sile ore lo sa se, nitoripe jeje ni en ti o gba epo sile n'o. t en t o wa lori o e a a so pe i ba o bi sile, gegebi o si ti je on a re ema o ya o ba gb s le si mba ona t re lo tab a h e ran ni eru ko d ijo bon bi ? "Idi oro mi niyen.

N e s i o pari oro re t n gbogbo awon agb la-ti o wa lati pari oro na kunnlo yungba won fi eti ko eti oba si pe enikeji wipe bawo ni tire tije ?

Enikeji dahun pe oro temi loni po, i b a aleye ti mo fe se ni pe eniti o gba epo sile ni eniti o jale. Se nigbati o le ba gun oke aja lati lo gbe epo nigbati ko ba ri e iti yio gba epo ju sile yio si sokale temi ko ju be lo.

Awon agbalagba ho lo ku u, nwon ni iwo omode wi're. Nitoto agbepo loja ko le gb epo ani ki o tun sokale, sugbon iranlowo ti eniti o gba epo na sile lowo re fun lo fi le gbe epo lo.

Nitorina "Agbepo laja ko jale, e iti o gba a ile-wo re sile yen gan ni olosa.

# Owe Yoruba

Oju ni a nmo aisi epo enu ni a nmo yo, obe ti ko ni eran iduro ni anmo.


DAGENITE
BATTERIES
give you a longer run for your money!



# Itan Ogbon Ati Lakaye

## (Lati Owo J. K. Azeez)

Ọpọlọpọ enia lo wa ti ko mọ iyatọ larin Ọgbọn ati lakaye, nitorina itan kekere ati iba alaye ti mo nṣe yi yio fun ni loye gbogbo rẹ.

Ẹniti o ba ni ọgbọn ti ko ni lakaye ọgbọn na ko le yọ. Ẹniti o ba ni lakaye ti ko ni ọgbọn on na ni a npe ni alagbara ma lero baba o ẹ.

Nitori na mo fẹ ki ẹ mọ wipe lakaye ni o fi ngbe ọgbọn yọ, nigbati ko ba si lakaye kini ao fi gbe ọgbọn wa pọ sita?. Nigbati ko ba si ọgbọn ewe, kini ao fi lakaye gbe sita? Nitori eyi la ṣe wipe 'Ọtun wẹ osi, osi wẹ ọtun ni ọwọ fi nmọ''

Ẹniti o ni owo, o ni ọgbọn ki o to ni owo nitori ṣugbọn ti ko ba mọ ọna ti o tọ lati na wo na si yio run patapata, eyi ni si pe ko ni lakaye.

Ni ọjọ kan, lakaye ati ọgbọn mu ara wọn lọrẹ awọn si pinu lati ma ṣe owo tabi ọja tita. Awọn mejeji bẹrẹ si jiyau ẹgbẹ bayi pe bi ọgbọn ba ni on ni agba, lakaye a ni on ui, Ti awọn mejeji ba si nlọ si ọja si ẹniti a fẹ ru igba ọja wọn. Nigbati o ṣe nwọn fi ero re bi ẹnikan ba lọ si ọja loni ẹnikeji yio lọ ni ọjọ mẹsan nitoripe ọja lekeleke ti nwọn nna ọjọ mẹsan mẹsan ni nwọn nna.

Nigbati o di ọjọ kan Lakaye gbe ọja wọn lọ si ọja lọ ta, o ta gbogbo rẹ tan. Nigbati o di ọjọ keji ti ọgbọn, ọgbọ tun gbe lọ, ṣugbọn ko si ẹniti o tilẹ bere pe kilo nta nigbati o wa di akoko ti ọja fẹ tu ni Ọgbọn wa pin lati ta iawin fun ẹnikeni ti o ba fẹ bayi ni Lekeleke kan wa ra iawin lọw rẹ ti o si ba pinnu lati san owo na lọjọ ọja ti yio tele e.

Nigba i Ọgbọn dele ti o ohun fun Lakaye gẹgẹbi Ọja ti ri Lakaye si bere lọwọ rẹ eniti o ta ọja awin fun Ọgbọn sọ pe Lekeke kan ni. Gbogbo enia si ti mo wipe bakana ni gbogbo Lekeke funfun lauiau

(Wo yoku loju ewe kefa)

# Otito Ni Olori Iwa

## (Lati Ọwọ O. Oluwo)

Awọn ọmọde mẹta nṣe ọrẹ pọ nigbakugba ni ile ọga wọn, Ekinni njẹ B'ojuri ẹnu apamọ, Ekeji njẹ Bojuri ẹnu asọ'' Ẹkẹta njẹ Aṣorodi bi iṣu mẹta, Ni ọjọ kan bi wọn ti nṣerepa wọn digbolu jinginla ti o wa ni agbala ọga wọn jigi na yi lulẹ o fọ tutu. O di womi nwo ọ, Ekinni ti a npe ni Bojuri ẹnu a apamọ damọ an wipe ẹnikẹni ninu wa ko gbọdọ jẹwọ bi jigin na ṣe fọ, bi ọga tilẹ ma lu awọn pa. wọn ko gbọdọ tu aṣiri yi.

Ekeji ti a npe ni Bojuri ẹnu asọ wipe o san wipe ki awọn jẹwọ asiṣe wa ki ajiya diẹ nisisiyi ju pe ki a purọ lọ ti yio jadi ni ọjọ m ran, ki a ma ba jẹ a-jẹ pe le iya lọjọ ti irọ na ba ja.

Ẹkẹta ti a npe ni Aṣorodi bi iṣu mẹta dahun wipe aṣiri yi soro ibo igbati ohun wa ko jẹ ọkan Ekinni nfẹ ki a ṣe, ekeji nfẹ ki a jẹwọ emi ko fẹ ki a purọ ki a ma ba-ba ọrukọ wa jẹ lọdọ ọga wa ati lọdọ awọn ara adugbo wa nitori e ọjọ ti irọ baja ẹnikẹni ko ni gbẹkẹ le wa mọ Lọna mej ao si sẹ si ọdọ Ọlọrun ti o ri w ni sisiyi, emi ko si fẹ ki a jẹwọ nitoripe inu yio bi ọga wa to bẹ ti yio fi le nawa pa, osi le-le wa sita

Ọrọ yi so ọgbọ.. kọ o so aṣiwere kọ tọhun-tẹnu ni ọga wọn wole de o ba won nibi pero yi lojukanna 'Boju ri ẹnu asọ, dọbalẹ O bẹrẹ si ọga rẹ

(Wo yoku loju ewe karun)

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE L'ayo!




Ti o ba ṣepa Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, bo si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun ṣaje-sise, inà-titàn ati lati mà fi yáná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 918 SATURDAY April 25—May 1 1964


## ORO OLOTU:

# Barika De Salah

AFI ikede wa ọse yi ki gbogbo Musulumi jakejado ilẹ Nigeria, ku ọdun Ileya, ẹ ku iyedun, Ọlọrun Ọba ki o jẹki gbogbo wa ṣe ọrọ ọdun yi pẹlu owo ọmọ ati alafia ara. Ni ọjọ Wednesday ọjọ kejilelogun oṣu yi 22, April 1964, ni a ki irun ọdun ti ilu Mẹka ti gbogbo awọn Musulumi jakejado igun mẹrẹrin aiye si ki awọn na papa ti wọn si ọpẹ fun Oluwa ti nwọn si pa odindi ẹran agbo gẹgẹbi aṣẹ Oluwa.

Ki Oluwa Ọ ọrun gba sara olukuluku wa ki o si gba adura wa pẹlu.

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn fi ile ebi ati ilu wọn silẹ lati lọ ṣe oranyan ẹsin Islam eyiti a mọ gẹgẹbi irin ajo lo si ilu Mẹcca ati Medina. Ki Oluwa sọ gbogbo wọn pada wa bawa ni alafia.

## Awon Dokita Ti O Ju Ise Sile Pada

BRUSSEL — Gbogbo igun ọgọ awọn dokita ninu ti nwọn mbẹ ni ilu Beligium ti nwọn bẹrẹ da iṣẹ silẹ lati ibẹrẹ oṣu yi ni ebo irohin wipe nwọn ti pada si ẹnu iṣẹ wọn lati ọjọ Satide ti o koja yi.

A gbọ wipe ko si nkan ti o fa a ti nwọn fi da iṣẹ silẹ ju fifi ti Ijọba fi'u na gbe jade fun awọn ti npa gbogbo ti nwọn gba owo alaisan.

Awọn alamojuto iṣẹ Ijọba ilu na paṣẹ wipe awọn ti lati ma ṣe iṣe awọn ọkita na wo, nwọn ko si ta gba owo lọwọ awọn alaisan ju iye ti awọn ba pa laṣẹ fun wọn lọ.

Nipa rogbodiyan na awọn dokita fun Ijọba nile awọn alaisan, nwọn bi ero kan jẹ eyi si jẹ ki Ọ ọpa mu wọn timọle.

Awọn obirin ilu na ko dabi awọn ti wa, wọn rawere ti nwọn ti njuko ọ ọ bu-ruku si awọn dokita oni-segun na wipe ki nwọn pada senu iṣẹ wọn ti nwọn ko ba fẹ wahala ninu ile wọn.

Wahala ti awọn ara ilu Beligum fun awọn dokita na ko ṣe fẹnu sọ; awọn ara ilu na lo jẹki awọn tete pada senu iṣẹ wọn.

# Iwe Si Olotu

## Agbe Kan Mu Emu Yo Sorun

IPARA (leti Shagamu) — A gbọ yanu ni gbogbo awọn ti nwọn wa si kotu awọn Ọlọpa gbọ gbogbo kulẹkule ọrọ okunrin agbẹ kan ti oruko rẹ njẹ Debanwa Ashade ti nwọn sọ wipe ko ni onjẹ kọn ju ẹmu mimu lọ, emu na lo si mu ku lọjọ ti o nti oko bọ wa si abule wọn.

Awọn ọlọpa Shagamu ti nwọn gbe oku rẹ lọ si ile awọn lakuluku ni nwọn fi iwe pe ẹgbọn rẹ, Taiwo Ashade ti nwọn jọ agbe pọ wipe ki o wa sọ tẹnu rẹ nipa iku ojiji ti o pa aburo rẹ ni iwaju adajọ kotu awọn ọlọpa Oloye O.A Okenla.

Taiwo ẹgbẹ na ni aburo on ni Debanwa ti o ku na, o ni ko si nkankan ti o pa ju ọti amuju lọ. O ni awọn kilọ fun un titi ko gbọ. Taiwo ni bi aburo on ba ti ri ọti emu o le ma jẹun fojọ mẹta.

Taiwo ni bi Ologbe aburo on na ba si fẹ jẹun ninu ko lọ ra iresi tọrọ na tan lawo.

Taiwo tun ṣe al ye fun adajọ ti o pa agbẹ na, o ti mbọ ti o ru apẹrẹ gbagada ti iyawo rẹ yio fi ri gari ti awọn yio jẹ.

Pẹlu inu ofifo ni aburo on kọṣẹ, ti o ṣubu. Ere ni, awada ni, ibẹ ni o ti yọ sọrun ni apapandodo.



Okunrin Alagbara ti o nfi Ehin Gbe Irin nigbati o nse Ere Idaraya

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

## Awon Osise Reluwe Nja Nitori Awon Oselu

EBUTE—MẸTTA...Ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ o elu tuntun ti nwọn s ṣẹ da sjlẹ ni Ibadan ti nwọn npe ni Egbẹ Dẹmọ ni a gbọ wipe o fẹ da ịja silẹ larin awọn osịsẹ Reluwe ati awọn osisẹ ebute Apapa ti nwọn nsịṣẹ ni idị ọkọ oju omi.

A gbọ wipe o le ni irinwo enia tị nwọn ti bina kuro ninu awọn ẹgbẹ na ninu awọn ọmọ ẹgbe ti nwọn n s ị s e Lebute nị Apapa p ẹ l u ọgba loko.

Nkan ti a gbọ wipe o fa ọrọ na nị wipe nwọn nị Alhajị H. P. Adebọla tịṣe olorị awọn oṣịṣẹ Reluwe na fi nkan nipa fun wọn wipe nwọn n lati wọ ẹgbẹ na pẹlu ịpa.

Ọgbẹni Michael Imoudu tiṣe alakoso a w ọ n osịṣẹ na nị ọrọ--korọ ni iwa ki a ma mu enia nịpa lati sẹ ẹgbẹ ti ko fe ṣe.

A g b ọ w i p e Alhaji Adebọla ni irọ ni nwọn npa mọ on on ko sọ wipe ki ẹnikan wa ṣe ẹgbẹ oṣelu apapandodo k a n. O n i awọn ọta on ni nwọn fẹ ba on jẹ ni.

Ọgbẹni M Fagbemi tị o ti tse akọwe awọn osisẹ akọwe loko rị ni opolopo ni awọn ọmọ ẹgbẹ osiṣẹ awọn ti nwọn tị mbọ fi ẹgbe osịṣẹ Resịẹ lọ sinu ẹgbẹ titun nitori ọrọ ni nnan ti nwọn ṣe ẹgbẹ oṣelu ti a ko fe ṣe

Ọrọ wọn na ko tị [illegible] a tị nkọ ti [illegible]

## Otito Loieri Iwa

(O bẹrẹ lojụ ewe kẹta)

bẹ fun idarijin o jẹwọ bị jigin a ṣe fi gbogbo wọn si se ẹẹ gẹgẹ ọga wọn lọnu iti ko fe na wọn ko si fẹ fi wọn silẹ patapata.

Ni orin o pinu lati g[illegible] dan owo jag n lọwọ wọn. Nwọn dapẹ lọwọ ọ ti wọn si jade Bọjuri ọmọ iso dan ọran wipe kị nwọn ba le ri owo ti a bu fun wọn ṣe b wọn si san owo na agiri yi bo dandan. wọn lo lọwọ iya ntorí awọn owo ẹsẹ ti wọn ṣe ẹgbẹ wọn.

# Eleti-Ofe D'araba




PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of siding) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL






# Eleti-Ofe D'araba

## Itan Ogbon Ati Lakaye

Nigbatį o dį ọjọ kẹsan, lakaye tun pe ọgbọn kio lọ gba owo Ọja Ijelo wa ni Ọja nigbati ọgbọn de ọja o bere sį bere ẹnitį o ra ọja awįn lowọ on ṣugbọn ko jewọ fun mọ pe on ni

Bayį ni ọgbọn wa sįle , ẹlu ọwọ ofo, o si va s ọ fun lakay wipe on ko mọ enįti o ra ọja lọwọ on mọ Inu bi lakaye O si pinnu lati ba ọgbọn qe ọja ni ọja ti mbọ.

Nigbati o di ọjọ Ọja tį o ma telee nį Lakaye gbe Aṣia pupa ati opolopọ aṣọ ododo dani b o tį de ọja o ta aṣia na pẹlu aṣọ ododo na mọ igi sį Ogun oja ni ibe ni gbogbo awon ẹyẹ Lekeleke ti wa ko ara wọn jọ lati wo iran ola yi.

Bayį ni Lakaye wa agogo ọwọ rẹ o sį wi fun won ki nwọn fe i de pe on fẹ sọro fun won gẹgẹbį Ọba ilu ti ran on wa lati ilu won o si bẹrẹ sį ba won sọrọ bayi pe 'M o k gbogbo ẹnyin Lekeleke wa ati ewa yįn wu mi pupo ṣugbọn mo fẹ kẹ mọ wįpe Aiṣamọ dara o ku ijo enia rẹwa o ku bi iwa Aja Oyinbo re wa o ku sibi i a Aja Oyinbo rewa o ku sibį ati ṣọdẹ Ben kinį kan ni Aiswo jẹ apa rẹ gun itan lo Ilu ki kere kį c m a ni Oleri ṣugbọn bi okikiyįn ti kan to e ko ni oba Nįtori ioi eyi nį Ọba iin wa se Ipaṣẹ fun mį Iatį wa ba yin soro ki enu si mọ ẹniti Ọba o to si

E Ka

**Itan Otito Ni Olori Iwa**

Lọjẹ ewẹ kẹta




Our tradition is based on principles of lasting validity: Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.

MERCEDES-BENZ



DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# Alhaji Adegbenro Di Olori Alatako

IBADAN—Ijọba Ilẹ Yoruba Wester Hous of Assemby tị fi ọwọ si wipe awọn gba HADJI Dauwda Adegbenro gẹgẹ bi Olori Alatako Ijoba Iwo-oru Oloye S. A. Akintọla ni o wi. Irohin wa sị eti gbọ awọn oselu ninu ịpade ti wọn nsẹ lọwọlọwọ ni ịsin sin yi ni Ibadan.



Alhaji D. S. Adegbenro

Oye owo ti Alhaji yị ma gba ni ọdun jẹ £1,500 pẹlu awọn ero oja tị enikẹni tị o b wa ni inọ bẹ ngba HADJI Dauwda opẹ pupọ ninu awọn olotu Ijọba fun aye na.

# West Appoint Three Senators

At a joint meeting of the western legislatune now sitting at Ibadan the House apbroved the recomendation of three prov mnet people to be senators in the uppe house of the Nigerian Parlament.

The senators are Chie Richard Afolabi Babalọla Chief James Makinde and Chief J A O Akande.

# Olopa Obinrin Lori Esin



CMDN Calheri Evans tị a nwo aworan rẹ lori ẹsin yị ni ọlọpa obinrin ti o kọkọ gun ẹsin iṣẹ ni Marchester nilu Oyinbo.

Caiherire ti bẹrẹsị gun ẹsin nigba ti o wa ni ọmọ ọdun mẹje ki o to wo iṣẹ Ọlọpa ni oṣu March ọdun togọja ịṣẹ olutọju lo ti nṣe tẹlẹ ri.

Read

And Advertise in Eleti Ofe

Weekly newspaper

A KÀN A NI ILẸ NIGERIA — ni ile-iṣẹ mọ̀tò-kikàn kini ti a kọ́kọ́ kọ si ilẹ Nigeria, ti o si tobi julọ.

Ó PỌ LORIṢIRIṢI — kò si ohun ti enia fẹ lo mọ̀tò fun ti kó ni ri Bedford to bá iṣẹ na mu.

A KAN A NI IFẸMIDIJE, a pilẹ kàn a ki ó le ba ilò ti ilẹ Nigeria mu.

# MỌ́TÒ BEDFORD

ON NI MỌ̀TÒ TO NTÀ JULỌ NI ILẸ NIGERIA — mọ̀tò Bedford ló pọ̀ tó nnú ọ̀na ju oriṣi mọ̀tò yoku lọ.



JU GBOGBO RẸ LỌ—a lè ri irin'ṣẹ Bedford rà tabi tunṣe jake-jado ilẹ Nigeria ni ibi-iṣẹ.

**Niger Motors**

NIGER MOTORS to wa ni: Eko, Apapa, Ibadan, Benin City, Onitsha, Enugu, Aba, Port Harcourt, Jos, Kaduna, ati Kano.


# Ijoba Ghana Fi Ofin De Owo Mole

**ACCRA** — Gbogbo awọn ọmọ ilẹ Nigeria ti nwọn nṣiṣẹ ni Ghana ni … bẹrẹsi kegbe … kiri wipe ko sọna ti awọn le gba fi owo sọwọ sile nitoripe Ijoba ilu Ghana ti fi ofin titun de owo ilu wọn mọlẹ.

A gbọ wipe o to ẹgbẹta ọmọ Nigeria (6,000) ti awọn ngbe Ghana, ibẹ ti awọn bi … wọn mịran si. Bi o ti wu ki o ṣiṣẹ to o ko gbọdọ fi owo ranṣẹ si awọn enia rẹ nile

Gbogbo awọn ọmọ Nigeria ni nwọn sọ nkan ti oju awọn nri lori ofin tuntun na fun asoju Ijọ-Nigeria; Alhaji Isa Wali nigbati o nṣe abẹwo kakiilu Ghana lati ba awọn ọmọ ilẹ Nigeria sọrọ.

Awọn ọmọ Ghana paapa ko gbọdọ mu ju pọnun mẹwa lọ kuro ni ilu ti nwọn ba nlọ si idalẹ.

# Aseku Pani L'obinrin

Lati Ọwọ S. A. Ogunmọla

"Ibiti Leke … ti nfo aṣọ re Olodumare ko fi han aparo, bẹni … koja idaru enia" Ni akoko kan, … wa ti a npe oruko rẹ ni Agiri-Aṣaṣa, ọkunrin yi si ni ekiki … ilu nitoripe tọmọde … sere ati awada. Ọba ilu papa ọkunrin agbe yi o si … rẹ dọba tobẹ to jẹ pe ọba ko le ṣe … fun odidi ọjọ mẹta.

Ọkunrin yi ni iyawo kan ti a npe ni A… atẹnijẹ, ki Olodumare ma jẹ ki a ri ẹni ti iyio ba … wa jẹ o.

Bi ọkunrin yi ba nlọ ni igboro ilu tọmọde-tagba ni yio ma ki i ni oriki rẹ bayi pe "Agiri – Aṣaṣa Aṣaṣa giri Oke tẹ kun rin ẹdọ mọlẹ on na a si tun da wọn lohun wipe ẹhin okika koni dara Nigbati "o ba lọ ki ọba ni Afin bakanna ni ọba ma ki i ni oriki rẹ on na a si tun da lohun wipe ẹhin oṣika ko ni dara. Bayi ni awọn Olofofo wa sọ fun ọba pe ki ọba ṣe akiyesi iru ebu … ti Agiri ma nbu ọba nigba gbogbo pe "ẹhin oṣika ko ni dara"

Iyoku di ọsẹ ti mbọ

# Eleti - Ofe D'araba

# E Ka

**Oro Alhaji ti Olala ri Anabi**
**(Loju ewe Kinni)**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street; Phone 23370; Editor, (Ol tu) Ọ.a Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467 Lagos.